“Ko si ẹrú kan ti Ọlọhun fi ṣe alaṣẹ lori awọn kan, ki o wa kú ni ọjọ́ ti o maa kú ti o si n tan àwọn ti wọn wa ni abẹ rẹ jẹ, àfi ki Ọlọhun ṣe alujanna ni eewọ fun un”

Láti ọdọ Mah’qil ọmọ Yasaar Al-Muzaniy- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Mo gbọ ti ojisẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ pé: “Ko si ẹrú kan ti Ọlọhun fi ṣe alaṣẹ lori awọn kan, ki o wa kú ni ọjọ́ ti o maa kú ti o si n tan àwọn ti wọn wa ni abẹ rẹ jẹ, àfi ki Ọlọhun ṣe alujanna ni eewọ fun un”.

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ pe ẹni kọọkan ti Ọlọhun ba fi ṣe olori fun awọn èèyàn, boya o jẹ àṣẹ ti gbogbogboo ni gẹgẹ bii alaṣẹ ìlú, tàbí àṣẹ ti kii ṣe ti gbogbogboo, gẹgẹ bii ọkùnrin ninu ile rẹ, ati obinrin ninu ile rẹ, ti o wa ṣe ohun ti o kù díẹ káàtó nibi ẹtọ́ àwọn ti n bẹ ni abẹ rẹ, o tun rẹ́ wọn jẹ, ko si gba wọn ni imọran, o wa fi iwọ̀ wọn ti ẹsin ati ayé ráre, o ti ni ẹtọ́ si ìjìyà ti o le koko yìí.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/5335